**ILE IGBIMỌ ASOFIN IPINLẸ ỌYỌ**
ORILẸEDE NAIJIRIA

IGBIMỌ ILE KẸJỌ
IPELE KEJI
NỌMBA ÒKÀNLÉLÓGBỌ̀N

# IWE AKỌSILẸ IFẸNUKO IJOKO ILE

**OJORÚ, OJO KEJO, OSU KEJI, ODÚN EGBẸ̀WÁ LÉ MẸ́TADINLOGUN**

1.0 Ilé jókŏ ní aago mokanla ku iseju marun. Alága Ilé jókòó, osi gba adura.

## 2.0 ÀKỌSÍLẸ̀ ORÚKỌ:

## 2.1 ÀWỌN TÍ O WÁ:

(i) Ọlọ́lá Aṣòfin A. M. Adéyẹmọ- Alága Ile (Ìlà Oòrùn Ìbàràpá), APC
(ii) Aṣòfin A. Músáh - Igbákeji Alága( Ìwọ̀ Oòrùn Sakí), APC
(iii) Aṣòfin K. H. Subair - (Gúsù Ìwọ̀ Oòrún Ìbàdàn Kinni), APC
(iv) Aṣòfin J. O. Ojo - Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó kéré jú (Oríire), LP
(v) Aṣòfin W. O. Akinmoyede - Akójanu Ilé (Lagelu), APC
(vi) Aṣòfin S. O. Àjànàkú - Alága Ìgbìmọ̀ gbogbo Àwọn Aṣòfin (Gúsù Ìwọ̀ Oorùn Ìbàdàn Keji), APC
(vii) Aṣòfin O. A. Oyatokun - Igbá Keji Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀jù lo (Afíjió), APC
(viii) Aṣòfin J. A. Olaleru - Igbá Keji Akójanu Ilé, (Kajola) APC
(ix) Aṣòfin G. J. Oyekola - Akójanu Ẹgbẹ (LP) Àtìbà,
(x) Aṣòfin A. K. Ọlọ́ya - Akojanu Egbe (Àríwá Ilà Oorùn ÌbàdànKínní), ACCORD
(xi) Aṣòfin S. A. Olalere - Ìdo, (APC)
(xii) Aṣòfin S. O. Oguntade - Ẹgbẹ́dá, (ACCORD)
(xiii) Aṣòfin A. Oseni - Ìrẹ́pọ̀ ati Ọlọ́runsógo, (APC)
(xiv) Aṣòfin (Iyaafin) B. O. Agbaje- (Ariwa Ìbàdàn Kínní), APC
(xv) Aṣòfin A. W. Adéoyè - Àríwá Ilà Oorún Ìbàdàn Kejì (ACCORD)
(xvi) Asofin M. A. Wahab - Oluyole, (APC)
(xvii) Aṣòfin R. A. Jimoh - Àríwá àti Àarin Gbùngbùn Ìbàrápà, (APC)
(xviii) Aṣòfin (Iyaafin) B. O. Oladèji- Aríiwă Ògbómọ̀ṣọ́, (LP)
(xix) Asofin B. S. Badmos - Akínyẹlẹ Kejì, APC
(xx) Aṣòfin P. O. Oyetunji - (Ogo-Oluwa ati Surulere (LP)
(xxi) Aṣòfin B. A. Azeez - Ọ̀nà-Àrà, (ACCORD)

(xxii) Aṣòfin O. S. Akande - Gusu Ogbomọṣọ (LP)
(xxiii) Asofin A. A. Ige - Gusu Ila Oorun Ibadan Keji), ACCORD
(xxiv) Asofin M. A. Sangodipe - Ila Oorun Saki ati Atisbo, APC
(xxv) Aṣòfin S. A. Okunlola - Ìwájọ̀wá, (APC)
(xxvi) Aṣòfin J. Oyebamiji - Akínyẹ́lẹ́ Kinni, (ACCORD)
(xxvii) Asofin L.O. Balogun - Oorelope, A.P.C.

2.2 ÀWỌN TÍ KÒ WÁ:

(i) Aṣòfin A. A. Ọládípọ̀ - (Aríiwá-Iwọ̀ Oorùn Ibadan), Akójanu Ẹgbẹ APC,
(ii) Aṣòfin O. O. Ọláléyẹ - Àríwá Ìbàdàn Kejì, (APC)
(iii) Aṣòfin M. O. Olagunju - Iwọ̀ Oorùn Àti Ilà Oorùn Ọ̀yọ́, (ACCORD)
(iv) Asofin A. F. Adesina - Gusu Ila Oorun Ibadan Kinni, (ACCORD)
(v) Asofin A. A. Adeleke - Ìṣẹ́yìn ati Ìtẹ̀síwájú, (APC)

3.0 FIFI ỌWỌ́ SÍ ÌWÉ ÀKỌSÍLẸ̀ ÀTI ÌFẸNUKÒ ÌJOKO ÍLÉ:

Àlága Ilé se ìkéde wípé òun tí ye Ìwé Àkọsílè àti Ìfẹnukò Ìjoko Ọjọ́ Isegun Ọjọ́ Keje, Osù Keji, Ọdún Egbewa le Metadinlogun wo, ó si bèèrè fún àyewo.

"Akiyesi waye pe ki oruko Alaga Igbimo Ilé lórí eto iroyin ti won sese yan, Asofin Oyebamiji Joshua ko wọ inu Akọsilẹ ní abala ikarun labẹ ikede leyin atunse yi.

Àbá wáye wípé, "kí a gbà Ìwé Àkọsílẹ̀ àti Ìfẹnukò ti Ọjọ́ Isẹgun, Ọjọ́ Keje, Osù Keji, Ọdún Egbewa le Metadinlogun wọle"- Aṣòfin K. H. Subair (Gúsù Iwọ Oorun Ìbàdàn Kinnì), Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀jù lọ.

Akéjì Àbá - Aṣòfin J.O. Ojo, (Oriire), Olori Omo Egbe to kereju lo. (LP)

Ìbèrè wáyé pé sékí á gba Àbáá na wọlé?

**<u>Ìfẹnukò</u>** wáyé lórí Àba

4.0 ÌFILỌ̀:

(i) Adari Ile ro awon Asofin lati maa wọ asọ ibile Yoruba (Buba, Sokoto, Agbada pelu Fila) ní Ijoko Ile ní Yoruba Ponbele.
(ii) Adari Ile fi to ijoko leti wipe eto ilera Pataki fun awọn Asofin yio waye lati Ojoru, Ọjọ́ Kesan si Ọjọ́ Abameta, Ọjọ́ Kokanla, Osu Keji Ọdún 2017 ni Aawe, Oyo.

5.0 FIFI AWỌN ALEJO HAN:

Alaga Ile ki awọn asoju Elesin Ibile ti wọn wa ni gbọngan Ile Asofin lati foju si ijoko Ile toni.

6.0 **YIYA ỌJỌ KAN SỌTỌ FUN ỌDUN ISẸSE YORUBA NI IPINLẸ ỌYỌ**

Aba waye pe ki Ile fi oju lameto wo ipo ọwọ ti ofin orilẹ ede wa fun awọn ẹsin mẹta ti wọn se pataki, pẹlu awọn eto ọlọkan ọjọkan ti ọwa fun ikọọkan awọn ẹsin Ọmọleyin Kiristi ati Islam ti ko si si fun ẹsin Abalaye, gẹgẹ bi yiya ọjọ kan sọtọ fun ọdun ẹsin bii keresimesi ati ileya – Asofin G.J. Oyekọla (Atiba).

Akeji Aba – Asòfin (Abilekọ) B.O. Oladeji (Ariwa Ogbomọsọ)

Ibere waye pe, se ki a gba Aba naa wọle fun ijiroro?

Ifẹnuko waye lati jiroro lori aba naa.

Ijiroro bẹrẹ.

Ibere waye pe se ki a gba Aba naa wọle.

**Ifẹnuko** si waye lori aba naa bayi wipe ki Ile pinu lati Rọ:

(i) Ẹka Alase Ijọba Ipinlẹ lati Ẹka Ile Isẹ Ijọba ti Iroyin, Asa ati Eto Igbafẹ lati gba ọrọ naa rọ pẹlu erongba lati jẹ ki aba yii kẹsẹ jari;

(ii) Awọn Asoju Elẹsin Ibilẹ lati fikunlukun mu ọjọkan fun Ọjọ Isẹse ni Ipinlẹ Ọyọ ti wọn yio si fi ransẹ si Ijọba fun fifi ọwọ si; ati

(iii) Ki ẹka Alase Ijọba Ipinlẹ Ọyọ fi ọntẹ lu ọjọ ti awọn Elesin Isẹse ba mu gẹgẹ bii Ọjọ Isinmi lẹnu Isẹ ati Ọjọ Ayẹyẹ Ọdun Ẹsin Ibilẹ.

7.0 **ASORỌ IJOKO ILE:**

Aba waye, "Wipe ki a so Ijoko Ile rọ di Ọjọbọ, Ọjọ kesan, Osu Keji, Egbewa Odun le metadinlogun ni agogo mẹwa owurọ" Aṣòfin K. H. Subair (Gúsù Iwọ Oòrún Ìbàdàn Kinni), Olórí Ọmọ Ẹ́gbẹ́ tó pọ̀jù lọ.

A so ijòkó Ilé rọ ní aago mejila koja iseju marun.

**Ọlọ́lá-Aṣòfin A. M. Adeyemo,**
Alaga Ile.